**Ọrọ agba**

ỌPẸKẸKẸTẸ ndagba, inu adamọ mbajẹ. Otitọ d'ọja o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.

# Irohin Yoruba

NO. 110 WEDNESDAY MAY 20 — TUESDAY MAY 26 1964 KOBO MẸTA 3D

**Akiyesi**

POLOWO ọja rẹ ninu iwe 'Irohin Yoruba' Oloyinmọmọ ti o nta ni ọja bi akara gbigbona.

### Ọṣun bọ ajaga ẹgbẹ Dọmọnu silẹ, ko ha tan bi?

# FUKẸ AKINTỌLA WỌ'MI

## ỌṢUN TAKU MỌ LỌWỌ

AKARA egbe Domonu ti Oloye Akintola Ise asiwaju re tu si epo ni Ilobu ni agbegbe Oshun ni ojo Abameta ti ise ojo kerindinlogun osu yi nibi ipade ita gbangba kan ti egbe Afenifere se ni ilu na nigbati egbagbeje awon enia ti o wa sibe lati origun mererin agbegbe Oshun ja iro egbe Domonu pe awon ni atilehin ni agbegbe na.

Oju egbata (6,000) enia ti o wa sibi ipade ita gbangba na. Lati nkan bi agogo mejila osan ni awon enia ti npese jo fun ipade na ti o ni lati bere ni agogo merin irole.

Lati Ẹrin ti ise ibuso kan si Ilobu ni awon onilu ni orisirisi ti wa fi ilu pade adele babasale egbe Afenifere, Alhaji D.S. Adegbenro.

Ninu oro ti o so nibi ipade ita gbangba na, Alhaji D. S. Adegbenro dupe lowo awon ara agbegbe Oshun fun iduro sinsin won lehin egbe Afenifere bi o tile je pe egbe Akintola nse orisirisi nkan abami ni agbegbe na lati je awon enia ti ko ba gba ti won niya.

O gbadura fun gbogbo won pe Olorun ko ni jeki won wo egbe ti o se oriburuku bi egbe Domonu, bakana na ni o tun gbadura fun won pe lukuluku ko ni pe omo won bi o ti se pa egbe Olomolangidi atipe Olorun ko ni jeki nwon se agbako asiwaju ti yio da omo won nu.

Alhaji Adegbenro kilo fun awon enia na ki nwon ma se sun rara nitoripe idibo yio wole de bi ole loru.

Lori oro ajosepo egbe Alakuko ati egbe Afenifere, o so pe Olorun ti o yo awon onirikisi ati odale kuro ninu awon egbe mejeji na ni Ipinle Iwo-Orun lo jeki ajosepo na waiye.

Saju, awon asiwaju egbe na ni orisirisi ilu ni agbegbe Oshun ti so pe itanje ni fun enikeni lati so pe Domonu fese rinle ni agbegbe na. Nwon so pe awon ara agbegbe Oshun ki ise odale ati pe awon ko ni se

(Wo oju ewe kejọ)

## Ijoba Okpara pe Ijoba Balewa lejo

ṢANGBA fọ ni Naijiria ni ojọ kejidinlogun oṣu yi nigbati oludamoran ofin Ijoba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria, Ọgbẹni Ibekwe pe Ijọba Apapọ Naijiria lejọ lori eto ikania ọdun 1963 ti Ijoba na gbe jade ni ibẹrẹ ọdun yi.

Ni owurọ ojo Aje yi ni Ọgbẹni Ibekwe pe ejọ na si ile ejọ ti o ga julọ ni orile ede yi pe Ijoba Apapo tabi awon aṣoju rẹ ko gbodo se

(Wo oju ewe kejọ)





Ki a sọ ni ṣoki nipe irọ egbe Domonu pe agbegbe Ọshun ni ibujoko won jadi ni Ilobu gegebi o se wa ninu irohin. Aworan oke yi ti ise apakan awon enia ti o wa si ibi ipade ko ha ti ja irọ na ndan?

Ẹniti a fi ami kamọ ni aworan ekini loke ni Alhaji D. S. Adegbenro. Eniti a fi ami kamo ni isale ni Ọgbeni Ayo Faanmi. Ọrọ na ko pariwo

Gbadun Ẹmi ẹ pẹlu

STAR




## Mẹrin moribọ ninu ẹjọ Awo

Ile ẹjo giga julo Naijiria ti so pe ko si ohunkohun ti awon mẹrin kan ti ile ẹjo kekere kan ni Eko ju si ẹwon pẹlu Oloye Awolowo ni oṣu kẹsan odun ti o koja lowo si ninu ẹjo ẹsun idite ati idulumo si Ijoba Apapo Naijiria ti a fi kan won.

Awọn olorire mẹrẹrin na ni Oloye Samuel Ọrẹdẹin, Ọlatunde Akamo, Josiah Ọlawọyin ati J. O Lawanson.

Ninu ọrọ Adajọ Agba orilẹ-ede yi nipa idasilẹ awọn mẹrin na, o so kederi pe ko si anfani kan ti o fi yẹ ki awon enia wọnyi wa ninu ẹwọn nigbati ko si ẹsun kan ti nwọn we mọ wọn lẹsẹ.

KO SI ẸJỌ

Ki adajọ to ju awọn enia merin na silẹ, o laye awon oniwe irohin pe ki iṣe pe gbogbo awọn ti o ku ninu ẹwọn nisisiyi ti jẹbi rara ṣugbọn ẹjọ ti wọn ni ayewo kinnikinni laini fi ẹjọ na fale rara.

Adajọ agba siwo fun ogbọn iṣeju ki o to pada wa sọ ninu ile ẹjọ pe, ko sunwọn rara lati da awọn merin na duro ninu ẹwọn.

O tẹnumọ pe awon adajọ ko ri eri kankan ti nwon fi so awon enia na si ẹwọn. Ṣugbon o fi idajọ awon enia to ku si Igba miran.

## Gbe asia Ẹgbẹ Afenifere ga

Oloye Obafemi Awolowo baba sale egbe Afenifere olori Alatako Ijoba Apapo Naijiria ti o wa ninu ewon odun mewa lori esun idite ati idulumo lati doju Ijoba Apapo dele so fun awon merin ti adajo agba dasile pe ki nwon o dupe fun Olorun, ki nwon si pada si agbegbe won lati ma tesi waju nipa gbigbe asia ogo egbe Afenifere ga.

Ọkan ninu awon ti adajo dasile' ogbeni J.O. Lawanson to gege pelu ayo nla lo si ibiti

(Wo oju ewe kejọ)

